# OBINRIN KAN BIMO IYANU SILE NILE IRE

UTC
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

6th & 7th
BOOKS
OF
MOSES
LEDE YORUBA
15/
A LE RI IWE YI RA NI
OSHODI COMMERCIAL
SERVICE
84, KING GEORGE AVENUE,
YABA
ATI NI
83, IDIKAN ROAD IBADAN

VOL. X No. 570 ELETI - OFE LAGOS. SATURDAY, MAY 3, 1958. KOBO MEJI (2d)

## Obinrin Kan Bimo Iyanu Sile Nile Ire

Ọladele ni a npe ọmọkunrin kan ara ilu Awẹ ti o sowo lọ si ọna ilẹ Ire, nigbati ọhun si dara fun o kuku fi ibe se ile o bimọ sibẹ o kọle o si kan-asẹ tabi kilo tun ku nwọn fi jẹ oye pẹlu.

Ladele ni iyawo kan ti o loyun sinu asiko ati bimọ obinrin na si ti to. Ladele kọ ila abaja o si jo baramu kan si ọwọ osi imu rẹ..

Nigbati o se Ladele bẹrẹ amodi laifa ọrọ gun o salaisi. Nwọn sin oku rẹ ni ọjọ keji. Nigbati o di owurọ kutukutu ọjọ ita oku na si iyawo re ti o ti loyun sinu bi ọmọ ọkunrin kan ti gbogbo enia nrọ gidijgidi wa wo.

Ohun ti o je abami lara ọmọ na ni wipe o kọ ila abaja wa lati ọrun o si dabe re lati ọrun pelu. Eyi ara! emimọ pelembe arugbo nyan ọkọ, eniti ko le rin ni ki a gbe on. Nigbati awọn oko ọmọ na jade nwọn fun ni Orukọ Babatunde Babajomu.

ỌRỌ RE O!

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbanigar, London.
Head Office Representative in London.
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Oloye Fadayiro Nilu Oyinbo



Baiyi a nwo ninu aworan yi ni Oloye B. A. A. Fadayiro ti iṣe Oloye Serekode (Chief Whip) ti Ile Igbimọ Iwọ-Orun ni Nigeria ti o lo kọ iṣe won ninu Ile Igbimọ nla (House of Commons) tilu Oyinbo.

Major Lockhart, akọwe egbẹ Ile Igbimọ ni o agbowọ lọwọ Oloye Fadayiro ninu Ile Igbimọ na ti a nwo yi. Osu meji pere ni yio lo ki o to pada wa sile.

## Oko Reluwe Jona

Ile Gadi (Guard's Van) ti o wa lara oko ti o kuro l'Eko ni ojo Alamisi ti o nlo si Kano o gbina ni Teson Minna, eru ati awon iwe ti a fi ran Post Office ni opo re jona.

# Oju Aiye Pe



Aworan yi ni akoko ti gbogbo awon oselu ile Nigeria nfe isokan ile Nigeria, ti nwon si ko ase won lo silu Oyinbo lati jumo se ofin ti yio jeki ile Nigeria wa ni isokan.

Lati owo osi:- Dr. Endeley, Oloye Awolowo, Sekiteri Agba. Lennox Boyd, Sardauna Sokoto, Sir James Robertson, Gomina Agba ati DR. Azikiwe.

ALAKOSO ILE INDIA FE FISE S LE



**New Delhi.** Irohin ti a ri gbo ni wipe Alakoso Ijoba ilu India Ogbeni Pandit Nehru (prime Minister) so ninu ile igbimo wipe on fe fi ise iselu sile lo sinmi.

Awon Igbimo ko wipe bi Ogbeni Nehru ba fe o le gba isinmi ki o tun pada s'enu ise. Awon igbimo tile fe fi enu sokan wipe "idagiri ni gbolohun ati fise sile na je fun awon" ninu ipade ti awon yio tun se. Ogbeni Nehru di omo odun mokandiladorin. (69 years)


## CARSON PAINTS AND VARNISHES

















SOLE AGENTS:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, BALOGUN STREET, LAGOS


# Itan Isin-'ku Iya Oduduwa

APA II

62. Gbogbo awon igi Oko lo nwo wa ki Oduduwa niti oku Iya re, Igi Iroko wa, Oruru wa, Opepe wa, Eki Abora Odan Ayunre Arere Araba Agbon-Igoti, ati orisirisi awon ako igi sugbon nigbati Igi Afomo mbo, ti on ti ade lori jigbinni.

63. Koiti yo si gbangba ode ile Oduduwa ti ariwo fi gba gbogbo ode kan wipe ka-bi-ye-si-o! Ba-ba-ye-o Oduduwa bere pe kini ere-di ariwo yi? Nwon si dahun pe oba nla kan ninu awon igi lo mbo wa ki Oduduwa.

64. Awon ako igi ti o mbo lodo oduduwa nse emimo larin ara won wipe tani oba igi ti o tun ju awon ti awon joko yi lo? Oduduwa wa bere si pa ile mo o ntun ile se o ntun ona se o nte aso o nteni lati gba alejo na ati awon emewa re si.

65 Igi Iroko nlari Araba nleri gbogbo awon ako igi nleri nile de iru ako igi na ti o mbo ti okiki re bo ti won mole bayi Agbon-Igoti se ileri wipe bi o ba lo je wipe igi kan ti ko nilari ni, nse ni on yio ko gbogbo won mi.

66. Nigbati o se ni igi Afomo yo si Afin Oduduwa pelu ade repete o de ade ele o wo agbada ofefee awon emewa re wo aso Onikoko. Oduduwa gba a si ese

67. Oduduwa wa bere si so bayi pe:-

Iwo Afomo, olorire ni o leni iwo si je omo kekere larin awon baba nyin ti o joko nwonyi gbogbo ako ati abo igi lo mo bi emi ti ti je pe oba ni emi je larin gbogbo enia Iwo si dide ninu ola nla re pelu titobi re lati wa fi ola re da mi lola ati lati fi gbe mi niyi, eyiti o yo ki awon baba nyin ti o joko nwonyi se ti nwon ko se nitorina lati oni yi lo mo fi o joye Oloja lori gbogbo igi oko.

(Wo yoku loju ewe keje)

# Otito Ha Ni Enia Ma Nri Oku

EKO Ọmọkunrin derebe mọto Taxi kan lo se irohin yi fun wa bayi wipe, on kọja lọ ni egbe Ṣọṣi Aguda beni on gbọ wipe "Driver, driver". bi on si duro beni Lady daradara kan wọ inu mọto o si wi fun on pe, ki ngbe on niṣo si Okun Alaṣla.

Nigbati a gunle si Okun Alaṣla, o bere lọwọ on wipe ngo tele on kalọ ki a jijọ mu faaji sere lọ tabi ngo duro de on, nitoripe emi na ni yio tun mu on pada lọ si Eko. Nigbati on gbọ bayi inu on dun boya on yio ri aye lati yọtọmi.

Beni on ba tiịkun mọto on pana ni on ba tele lehin On ko tete mọ pe Alara-meji enia ni on ba tele nṣe ni Oṣupa nja to. Bi awọn mejeji ti nlọ beni on fi ọwọ pan nidi, nṣe ni gbogbo ara on nṣana.

Ṣugbọn Lady na wa sọrọ kan eyiti o jeki gbogbo ara on rọ wẹsi. O sọ wipe bi on ba rin tele on ọwọ osi ni ki on ma rin si, nitoripe enia ko gbodọ te oiji on mole. Nṣe ni aiya on ja ti irun ori on ṣeṣe dide eyiyi jeki on fura wipe oku ni. On ko si gbodọ sa pada ki o ma ba ṣe on ni jamba.

On wa mbe wipe ki o kọ on ni egbogi ti on yio ma je titi lai. O si fesi da on lohun wipe kini mo tun nwa egbogi si nje gbogbo ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun on yi ko ha to fun on bi? Nigbati apada de egbe Ṣọṣi Aguda mo sọ fun pe ki o fi owo sile nigbana lo fi ede oyinbo sọ fun on pe next time. Iyen nj pe ao tun pade nigbamiran.

# Onje Yoruba Siwaju Ki Gari To De

Ṣiwaju ki awọn Payọn to mu gari de ilẹ enia dudu, iṣu ati agbado ati ẹwa ni Yoruba mọ ni onjẹ. Nwọn nfi iṣu guayan nwọn fi nṣe elubọ, nwọn si njẹ iṣu, nwọn fi nṣe akara ọjọjọ.

Nwọn nfi agbado ṣe ẹkọ, Ekuṣu, Akara agbado, ati Itakerẹ. Nwọn nfi ẹwa ṣe akara gbẹntu, nwọn fi nṣe Alapapa, Gbẹgiri Dọmbọrọ ati Tunpulu.

Gbogbo awọn akan nwọnyi ni a ti njẹ gẹgẹbi onjẹ nilẹ Yoruba ati awọn miran pelu ti a ko ranti kọ silẹ ki gari to de.

Nigba aiye oba Oṣilokun ni awọn Payan (Spanish) wa da oko gbaguda si isalẹ Iga niwaju oko Ojubuku awọn pada wa ni amọdun awọn si fi han awọn ara Eko bi nwọn ti ṣe nṣe Tapioka.

Ṣugbọn Yoruba ko mọ ṣe gẹgẹbi ti Payan ni nwọn ba fi ṣe ni gari gẹgẹbi o ti wa loni. Nigbati awọn potogi ri i nwọn pe e ni Garr. Eyi na lo di oruko ti a fi npe Gari titi di oni oloni.

**Kere o!**

Ati ni orisirisi ogun German to ṣeṣe de fun ọnirọru aisan tọkunto tọbinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

*Read this list of popular titles*



HMV YELLOW & RED DOG
6098 - Kelegbe Megbe/Odun Titun Owo Titun
„6099 - Agba Olorin/Busura Baba Oga
„6100 - Yawa Yesu/Ọmọlere Aiye
Jimo Ojindo & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-
1. Y A Bilesanmi - 87 Victoria St, Lagos
2. Animawu Stores - 24 „ „ „
3. Salawu Aremu - 73 „ „ „

HMV BLUE DOG
JZA 100- Shegbola/Ohewa Gbawa Lowo Iku Ojiji
„ 101 Bakare Alake/Ejire Baba Taju
„ 102 Raimi Oga Ota/Wahabi Baba Fasila
S. Aka & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-
Omobosi-Owo Stores
Lagos/Abeokuta

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

**E L E T I Ọ F E**
A-NJU-WỌN KO SE WI L'BIQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. X. NO. 573 LAGOS, SATURDAY MAY 3, 1958.

# Jamba Oko Ero Npoju!

Bi enia ba fi oju inu sekiyesi awọn jamba to ma nsẹlẹ lore-kore, ninu ọkọ ero ti oja omi tabi ti Mọto a o ri daju wipe jamba na ṣe npọ rekoja, de aye ti o yẹ ki Ijọba ba wa m'ojuto lati ma ṣe ayẹwo nigba gbogbo ki Ijọba to ma fun awọn Ọlọkọ-ero ni iwe aṣẹ fun iṣẹ wọn na.

Ọpọlọpọ ẹmi ni jamba ọkọ ero wọnyi ti fi ṣofo danu, yala ninu ọkọ ti oju omi t'abi ọkọ ero ti o nrin nilẹ bi Lorry, ati paapa ni pataki awọn awa'kọ (Drivers) tabi awọn ọga kọ (Captains) ti nwọn jẹ alaṣẹ awọn ọkọ ero wọnyi, ni o tọ. ti o si yẹ ki ijọba ri wipe awọn to, nwon si ni gbomgbo ki ijoba to gba wọn laye iṣẹ ọkọ ero ni ṣiṣe; nitoripe ọpọlọpọ ni ko bikita fun ẹmi ọmọ enia ẹlẹgbẹ re ayafi ki nwọn ti ri owo ni pataki.

Ki awọn ọlọpa oju-omi ati awọn ọlọpa olutọsọna awọn ọkọ ero fi agbara kun iṣẹ wọn lati le din awọn jamba ti o ma nṣẹlẹ na ku nipa bi bojuto ero ti awọn ọlọkọ nko kun inu ọkọ laibikita fun ẹmi enia.

O d'ọwọ yin o.

---

## Oriki Eso Ikoyi

Eso Ikoyi omo Agbonlona, ti ko nri iku sa elegba omo a sun pakiman lo'o ti a rogun oba. Eso ri ogun o yo sese mole Ore.

Eso Ikoyi ko n'e Okete, obinrin won lo nfi apa ewusa eko nile Olugbon, Sigo ni iba sa li ogun o tabi Sigo?.

---

## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Sile Meji Abọ 2,6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.

---

# Ojojo Nse Oba Obinrin



A gbo irohin ninu ose yi wipe Oba Obinrin Elizabeth Keji nse are tobe ti o ni lati kuro ninu Afin Buckingham lo si Afin Windsor, ojulo ferefe ni a gbo pe o fe fowo kan oba.

A gbo wipe nikan oba yoe lo se akpo si yi. Ogbeni Harold Macmillan ti o nse Prime Mister, lo ti fe lo joko sibe sugbon ijoko re ko bo si mo. Yio nilati lo ri oba ni ojo Jimo ti o mbo nibe.

---

### EDEKOYEDE BẸ S'LẸ LARIN LARUBAWA

FỌRỌLỌMI. A gbọ irohin wipe ede koyede kan bẹ silẹ larin awọn Larubawa apa ilẹ Sudan lori wipe ẹnikinni ko fẹ ki ẹnikeji wa ko eran ọsin tire mumi ni agbegbe odọ wọn eyi na ni ehun ti o di ogun ti o si di ọde ti awọn apa kini fi ṣigun ija si apa keji.

Ijọba Faranse ti o mbe ni Fotilọmi (Fortlamy) dide lati pari ijọ na awọn onija mejeji ko gba rara ayafi nigbati Faranse ta ibọn lu wọn ti nwọn si pa bi enia mẹkanla ti iwọn ogun enia si gbọgbẹ ninu wọn ni ija na to mu'po.

Ija na ṣẹ ni ebule kan ti o nje Fanabo ti ko ju iwọn ọgọta ibuso lọ. Ọrọ pataki ti awọn Faranse gbọ ni wipe apakan awọn Larubawa na ko gba ki awọn apakeji ko eran wọn wajẹko larin ẹkọ ti nwọn ti tinu-fẹdọ so.

### AJALA TUN BẸRẸ IRIN AJO RẸ

EKO. Irohin gbojikan wipe Olabisi Ajala ti o nse omo bibi inu Alhaji ati Alhadja Ajala eniti okiki re gbojikan kakiri agbaiye pelu moto olonrete kan ti o fi rin irin ajo na ti tun ko s'enu irin ajo re.

Sugbon iko nse on nikansoso lo bere irin ajo ti ori ekeji yi on pelu okunrin arinrin ajo miran ti nwon npe ni Hans Gunther lo jijo bere irin na lati Eko.

Bi a ti gbọ wipe nwon fe rin irin na lole yi ni lati Eko si Ba-Orun si Kano. Lati Kano si Fortlamy, Sudan Kongo, Egypt, India, Japan, China ati Resia yio pari irin ajo re ni ọdun 1960.

# Oju To Woran Gelede Pari Iran Wiwo

Lati Ọwọ Ọmọ Awori

Awọn ẹya awori pe oriṣi meji nisisiyi, nigba atijọ Ẹgbado ni gbogbo nwọn njẹ Ketu si ni Orile wọn. Alaketu ni ọba wọn, nigbati ogun de ni awọn tuka si apa eti odo tabi eti ọsa awọn miran wa ni ọgan tabi lọu fabo awọn Ẹgba lo fun wọn ni oruko ọtọtọ bayi wipe Awori Eredo, tabi Eti Ọsa, tabi awọn ti Ẹgan. Awọn nwọnyi lo parapọ di Awori awọn ti a npe ni Ketu ni awọn ti ilẹ Ketu. Awọn nwọnyi ko njẹ Awori mọ bikoṣe Ketu.

Orișa kanna ti a npe ni Gẹlẹdẹ lo wa larin awọn mejeji Orișa Gelẹde ti awọn Ẹgbado ati ti Ketu lo darajulọ ninu gbogbo awọn orișa ilẹ Nigeria. Oriṣiriṣi ni oruko ti nwọn fi npe awọn Olori awo Gelẹdẹ ti o ba jẹ Ọkunrin, gẹgẹbi gbelvefo; Agbori odo-ja-bi-oji Ẹleru meji Ojujo-Pewọ Agbeil ni-ti-ọmọri-Odo ati Ibomo.

Gẹlẹdẹ jẹ awo obinrin ati ọkunrin awọn ti o ngbe orișa Gelede ko nșe awo. Awo Pataki ti nșe ni inu re ni Bebe ti o ngbe sidi Obinrin ti o nșe Olori awo yi ni nwọn npe ni Iya-agberu awọn ti o ngbe orișa na ni nwọn npe ni Agbesijo. Awọn ako Gẹlẹdẹ ni nwọn npe ni Efẹ eyiti oruko re wọpọ ninu wọn ni nwọn npe ni Orișa-Ibeku tabi Amakoko nitoripe nșe ni orișa na gbe koko si enu.

Bi Gẹlẹdẹ ba fẹ jo nșe ni yio tete fo si gbalata ojutaiye fun gbogbo enia lati wo. Bi awọn orișị kan ba koja lọ awọn miran yio tun de ati nigbati orișa Gelede ba njo nșe ni enia yio lanu sile ti itọ yio fere le kan lenu re ko deiti si ere orișa kan ti o dun bi ti Gelede Enia fere le gbedura pe ki Gelede yi di obinrin ki on fa ni iyawo.

Ilu meji ni ilu Gelede

(Wo yoku loju ewe keje)

# Eleti-Ofe D'araba meji, Yio Se Ba Rele.



**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63 Massey Street, (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

# Oba Gesi Be Ilu Sweden Wo



Aworan Oba Obinrin ilu Oyinbo Gesi pelu Oba ilu Sweden, ti awon Oyinbo onisano, ati oko re, ololajulo Duke of Edinburgh ni asiko irin ajo won lo be ilu Sweden wo.

# Dereba Oko Ofurufu



Awon meta ti o duro gbe ara won yi ni awon omo ile Nigeria meta ti o nlo ko ise gegebi a ti se ngbe Oko ofurufu fo bi eiye lofurufu nwon ti mura irin ajo won nisisiyi nwon nlo silu Oyinbo fun eko giga nipa oko ofurufu.

**Bi Iwo Ba Fe Je'Gbadun**

**Ra Siga BICYCLE**

**Ti O L'okiki Nile Nigeira**



## ỌMỌBINRIN KAN WA BABA RẸ LỌ SILU AJIRAN

EKO Ọdọmọbnirin arewa kan lo wa baba re ti o ti ku lati ọdun 1922 lọ si ilu Ajiran nigbati o ṣe ngoke agba sibe ti koiti bimọ. Gbogbo awon ara rẹ ẹbi rẹ ati ibatan re gbogbo lo bimọ nile ọkọ ṣugbọn on nikanṣoṣo ni o yagan larin wọn on na lo si lowo ju ninu gbogbo ebi o lowo o ni aṣọ oko dukia pẹlupẹlu Alarede ni obinrin yi. Nigbagbogbo ni yio tilekun mọri ti yio si ma gbadura ki on le bimọ yi ṣa. Ọkọ re a si ma tu ninu ko si ile Oniṣegun ti nwọn ko de tan. Nwọn lọ silu Abarẹn pẹlu ọkọ rẹ, pabo ni. O wa gbero lati lọ ri baba re ni ilu Ajirọn bi o ba je pe, lotitọ ni wọn mba oku sọrọ nibe gegebi a ti gbọ.

Obinrin na dide lati lọ ba Baba rẹ sọrọ on pẹlu ọkọ rẹ wọn gunlẹ si ebute Ajiran ni agogo meji abọ ọsan, awọn wọ sinu ile. Lẹhin ti nwọn ṣe wọn ni alejo tan, awon pe bale ile ti nwọn wọ si, awọn ni ki o mu won lọ sọ ọdọ Ojomu Ilaṣe.

Bale ile na ki gbe hal ko nṣe ẹniti ọnia le ri bẹ ati pe yio to ọjọ mẹta ki awọn to le fi oju kan Ojomu nwọn si dahun pe awọn ko kọ. Laifa ọrọ gun, nwọn ri Ojomu nwọn si ba sọrọ. Ojomu ni ki nwọn pada wa ni agogo meji ọsan.

Nigbati nwọn pada de ibe, baba na so fun omobinrin na pe ki o pa eran kan fun on nibiti agbe bi on si, on mbo wa.

Obinrin ko ma osu na je, o si bimo obinrin, omo na si mbe titi di oni.

### E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Pelowo Oja Yin Sinu Re-

## Oju To Woran Gelede Pari Iran Wiwo

(O bere loju ewe karun)

Batakoto ati ilu Aran Olori onilu Aran ni awọn ope ni Adenji Apata Ṣinaba oruko onilu Batakoto ni Paya. Eyi ni ohun ti o di owe bayi pe oju ti o ba ti woran oriṣa Gelede ti pari iran ni wiwo. Gbogbo awọn oriṣa lo ni ole ati ẹrọ tirẹ. Bi oriṣa yi ti rọ bi ẹkọ ṣo yi, bi o ba binu si ẹnikan eje ni awọn o fi ba oluwa re ja.



No. 73/S.2/Vol IX/676

# Ministry Of Justice Western Region

## Vacancy For Assistant Director Of Public Prosecutions

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Assistant Director of Public Prosecutions in the Ministry of Justice Western Region.

Scale of Salary: — Group 6: £2 220.

For full particulars please see Western Region of Nigeria Gazette No. 28 Vol. 7 Notice No. 394 of 24th April 1958

Closing date 15/5/58

No. 64

# Public Notice

It is notified for information of the Public that with effect from 0800 hours on May 5th 1958 the Police Headquarters, Central Region, will be established at the Lion Buildings, Campbell Street, Lagos.

2. All Telephone numbers as published remain the same. The '999' Emergency System will continue to operate at all times.

3. The Central Region Police Headquarters at Tinubu Square, will close down on Saturday May 3rd.

**L. O. Edet**

Acting Asst. Commissioner of Police



# Iwora: Ara-O-Lin




O dara fun lakuregbe, ẹhin didun, ẹfori, otutu, ifọsẹrọ, itan riro ati orisirisi aisan miran ti o fi ara jọ wọn.

Ara-O-Lin yato si awọn ori miran ti a fi wora. Awọn Hausa gbadun rẹ tobẹ ti nwọn fi sọ ọ ni "Borokounu". Awọn Ibo fẹran rẹ ti nwọn fi sọ ọ ni "Ose". Awọn Yoruba si lẹ tobẹ ti nwọn fi sọ ọ ni "Ata", nitori riyẹriyẹ ti o ni. Wa ra tirẹ ni 2/6d lọdọ wa; ki o si ri iyatọ ninu iwora ajẹbi-idan ati nkan miran.

**Egba Trading Aradan Store**

18, Denton Bridge St. P. O. Box 2, Ebute Metta



# Oba Obinrin Yio Be Ghana Wo



LONDON. Iṣẹ'ijọba wa nibiyi o ri ... ọso pe ọba obinrin ilu Ọyẹl ati ọkọ rẹ yio lọ bẹ ilu Ghana wo ninu ọdun 1959. Dr. Nkrumah lọ kọwe si ọba na wipe ki o bẹ ilu Ghana wo.

Bi ọba na ba lọ sibẹ Ghana fun abẹwo na iyẹn ni yio di ẹrin ajo kejila ti ọba na rin kakiri agbaiye latigba ti o ti gori oye ọba ni ọdun 1952, o si wa bẹ ilu Nigeria wo ninu ọdun 1956.

Ninu oṣu March 1957 nigbati ile Gold Coast gba Ominira ti nwọn si yi oruko ile wọn pada si Ghana ni ọba ran ẹgbọn rẹ kan ti o jẹ olobinrin ti a npe ni Duchess of Kent wa si Ghana gẹgẹbi aṣoju Ọba fun iṣedi Ominira ilu na.

Ọlọrun ko da Ọba si, ki ọba pẹ titi.

# Ija Ifa Ati Esu

Ija be s'le larin meji Ifa ati Esu ni ode orun bi ija na tien sele ni pe Ifa ji ni owuro o nran pako eleta. Esu paapa ji o fe run pako nitori ko ri tire. Ibe lo ba sole Ifa ni ija ti awon ara orun le ti ko se la ti bere ni Olodumare ba fi le won silo aiye.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 23, ... Street P.O. Box 687 Lagos Phone